

Bringing our Cultures Home:

FESTSCHRIFT FOR BADE AJAYI AT 70

Ahmad Shehu Abdussalam (Editor-in-Chief)
Lere Adeyemi
Hezekiah Olufemi Adeosun
Bolanle Elizabeth Arokoyo

© Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilorin, Ilorin, Kwara State, Nigeria 2014

ISBN: 978-978-937-825-8

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced, stored in a retrieval system, transmitted in any form or by any means, electronic, mechanical, photocopying, recording, or otherwise, without the prior written permission of the publishers.

Printed and bound by
Chridamel Publishing House
No 3, Otunola Adebayo Street
Off Taiwo Road, Ilorin, Kwara State

AKITIYAN BÁDÉ ÀJÀYÍ LÓRÍ ÌṢÀTÚNPÍN ÌHUN ẸṢẸ IFÁ

ADÉỌṢUN, Hezekiah Olúfẹ́mi
Department of Linguistics and Nigerian Languages,
University of Ilorin, P.M.B. 1515, Ilorin, Kwara State, Nigeria.
hezekiahadeosun@yahoo.com

Àṣamọ̀

Ifá jẹ́ àkójọpọ̀ ọgbọ́n àti ìrírí àwọn Yorùbá. Oríṣiríṣi nǹkan nípa èrò ọkàn àti ìtàn àwọn Yorùbá ló sì pé sínú rẹ̀. Ẹsẹ Ifá ni àwọn ìtàn tí à ń bá pàdé nínú Ifá. Èròńgbà iṣẹ́ yìí ni láti ṣe àgbéyẹ̀wò ìṣàtúnpín ìhun ẹsẹ Ifá tí Àjàyí (2002) ṣe nínú iṣẹ́ rẹ̀ tí ó pè ní Ifá Divination: Its practice among the Yorùbá of Nigeria. Kí èròńgbà iṣẹ́ yìí tó wá sí ìmúṣẹ, a wo àwọn àkọsílẹ̀ tí ó tí wà ṣáájú ti Àjàyí (2002) lórí ìhun ẹsẹ Ifá, kí á tó wo bí Àjàyí ṣe pín tirẹ̀ nípa lílo tíọ́rì ìfojú-ìhun-a-so-pọ̀-mọ-ìsẹ̀lẹ̀-àwùj-wò. Àbájáde iṣẹ́ yìí fihàn pé àwọn onímọ̀ mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ takuntakun lórí ìpín ìhun ẹsẹ Ifá àti ìlànà tí wọ́n gbà fi pín in. Àwọn onímọ̀ náà ni Raymond (1964), Bascom (1969), Abímbọ́lá (1976) àti Ọlátúnjí (1984). Iṣẹ́ yìí gúnlẹ̀ pẹ̀lú àlàkalẹ̀ ọ̀nà méta gbòòrò tí Bádé Àjàyí ní a lè gbà láti pín ìhun ẹsẹ Ifá. Àwọn ọ̀nà méta náà ni ọ̀rọ̀ àkọ́sọ, ìtàn Ifá, àti ọ̀rọ̀ àsọkágbá. Ní èrò tiwa, ìlànà ọ̀tun yìí rọrùn díẹ̀ ju ti àtẹ̀hìnwà lọ láti pín ìhun ẹsẹ Ifá.

Kókó ọ̀rọ̀: ìhun ẹsẹ Ifá, ẹsẹ Ifá, ìṣàtúnpín, Bádé Àjàyí

Ìfáàrà

Gẹ́gẹ́ bí àríwòye Abímbọ́lá (1976:3), Ifá (tí a tún mọ̀ sí Ọ̀rúnmìlà) jẹ́ ọkan lára àwọn ọ̀kán-lé-nírínwó irúnmọ̀lẹ̀ tó sọ̀kalẹ̀ láti ìsàlú ọ̀run wá sílé ayé. Olódùmarè ni a gbọ́ pé ó fún ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ní iṣẹ́ tí yóò ṣe lórílẹ̀ ayé. Bí àpẹẹrẹ, Ògún ni òrìṣà tó wá bójútó ilò irin, ọdẹ ṣíṣe àti ohunkóhun tí ó ní ṣe pẹ̀lú ògún. Ọbàtálá dúró gẹ́gẹ́ bí alámọ̀ tó ń mọ ara ènìyàn kí Olódùmarè tó mí èémí ìyè sí i. Eṣù dúró gẹ́gẹ́ bí ọlọ́pàá tó ń dáàbò bo àṣẹ àti agbára àìrídìí tí Olódùmarè fi dá ayé, tí ó sì ń ṣe àkóso rẹ̀ pẹ̀lú òfin. Ifá ló ń bójútó àyẹ̀wò nítorí ọgbọ́n tí Olódùmarè fún un, òun ni ó sì wà lọ́dọ̀ Olódùmarè nígbà tó ń ṣẹ̀dá ayé (Ẹlẹ́buìbọn, 2004: vii). Nitorí náà, Ifá mọ gbogbo àṣírí tó pamọ́ nípa àgbáláayé, abájọ tí wọn fi ń kì Ọ̀rúnmìlà ní a-kéré-finú-ṣọgbọ́n. Abímbọ́lá (1977:vi) ṣàlàyé pé òpìtàn pàtàkì ni Ọ̀rúnmìlà nígbà tí ó fi wà láyé àti títí di òní-olónìí. Àti pé àwọn Yorùbá gbà gbọ́ pé Ọ̀rúnmìlá nikan ló mọ àṣírí bí Olódùmarè ṣe dá ayé àti ọ̀run. Òun náà ló sì wà níbẹ̀ nígbà tí ẹnikọ̀ọ̀kan fi ń yan ìpín tirẹ̀. Ìdí nìyí tí a fi ń pe Ọ̀rúnmìlà ní 'ẹlẹ́rìí ìpín' àti 'òpìtàn ilẹ̀ Ifẹ̀'. Akíntólá (1999:2) ṣàlàyé pé kò sí ohun tí Ifá kò fá tán nínú ìgbésí ayé èdá. Òun ni orísun ọgbọ́n àti atónà fún èdá nípa bí Olódùmarè ṣe ṣẹ̀dá ayé àti irú àjọṣepọ̀ tó wà láàárin ẹ̀dá èniyan, àwọn òrìṣà àti Olódùmarè, nitorí pé Ọ̀rúnmìlà ló wà níbẹ̀ nígbà tí Olódùmarè n ṣẹ̀dá ayé. Àjàyí (2002:2) náà kín èrò yìí lẹ́hìn nígbà tí ó sọ pé:

> The Yorùbá oral tradition emphasizes the part played by *Òrúnmìlà* in guiding the destiny of man and *Orìṣà*. One reason given for his intimate knowledge of matters affecting man's destiny is that *Òrúnmìlà* is present when man is

being created. Therefore, he knows all the secrets of human beings and the *Orìṣà* and thus he can reveal what has been destined for and if the destiny is an unfortunate one, *Ọ̀rúnmìlà* can prescribe remedies to avert the misfortune. This is why *Ọ̀rúnmìlà* is described as *Ẹlẹ́rìí-ìpín* (the witness of destiny or lot), *Òbìrìkítí A-pa-ọjọ́-ikú-dà* (the great one who alters the date of death).

(Ìtàn àtẹnudẹ́nu Yorùbá fi ipa pàtàkì tí Ọ̀rúnmìlà kó lórí àyànmọ́ ẹ̀dá àti ti àwọn Òrìṣà. Ìdí pàtàkì tí ó fi ní ìmọ̀ nípa àyànmọ́ ẹ̀dá ni pé ó wà níbẹ̀ nígbà tí Olódùmarè ń ṣẹ̀dá ènìyàn. Fún ìdí èyì, ó mọ gbogbo àṣírí ènìyàn àti ti àwọn Orìṣà, ó sì lè sọ àṣírí ohun tí a yàn mọ́ ẹnì kọ̀ọ̀kan, tí àyànmọ́ náà bá sì jẹ́ èyí tí kò dára, Ọ̀rúnmìlà lè sọ ọ̀nà àbàyọ kí àyànmọ́ náà yípadà di rere. Ìdí nìyí tí a fi ń pe Ọ̀rúnmìlà ní Ẹlẹ́rìí-ín, Òbìrìkítí A-pa-ọjọ́-ikú-dà).

"Òbìrìkítí-A-pa-ọjọ́-ikú-dà" túmọ̀ sí pé Ọ̀rúnmìlà mọ ohun tí a lè fi yẹ ọjọ́ ikú ẹni. Ọ̀wọ́nrín Méjì jẹ́rìí sí èyí pé:

Oníkẹ́kẹ́ logún
Alágbàjà lọgbọ̀n
Oníkolo làádọ́ta
A díá fún ọdúnmbákú
Tíí ṣọmọ bíbí inú Àgbọnnìrègún
Wọ́n ní ó rúbọ nítorí ikú
Wọ́n ní ó fadìyẹ ìrànà kan rúbọ
Ó ṣe é, ikú ò pa á...(Aṣáolú, 1981: 4).

Bákan náà, Asawale (2011: 3) sọ pé Ifá jẹ èsìn kan gbòógì láàrin àwọn Yorùbá, àti pé àwọn Yorùbá a máa bọ àwọn orìṣà mìíràn bí i Ṣàngó, Ògún, Ọ̀ṣun ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ nípasẹ̀ Ifá. Bí àpẹẹrẹ, bí ènìyàn bá lọ sí ọdọ babaláwo fún ìṣòrò kan, ó lè yọ sí i lójú ọpọ́n Ifá láti bọ orìṣà ilé wọn kí ó tó ṣe rí àyọrísí sí ìṣòrò tó dojúkọ ọ́. Ní èrò Aṣáolú (1981:3), ó ní "ohunkóhun tó bá rú àwọn ẹ̀dá lójú, Ọ̀rúnmìlà yóò là wọ́n lóyẹ̀ rẹ̀. Bí a bá ń ṣiṣẹ́ tí a kò ní àkójọ, Ọ̀rúnmìlà yóò sọ ohun tó fa sábàbí àti ohun tí a ó ṣe láti borí ìṣòro yìí. Bí obìnrin bá délé ọkọ tí kò tètè rọ́mọ bí, Ọ̀rúnmìlà yóò sọ ohun tó máa ṣe láti jẹ́ kí ó rọ́mọ bí". Aṣáolú (1981) tọ́ka sí ẹsẹ Ifá kan nínú Odù Ìrosùn Méjì látí kín èyí lẹ́hìn pé:

Elégédé ní í so kú-ń-dí kú-ń-dí lóko Ẹ̀gbá
Ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà abèso kọ̀ọ̀rùkọ̀ọ̀rù lóko Ẹ̀gbádò
Ẹ̀gbá ló yó tán
Ló múnú araa rẹ̀ dá gbẹ̀du
A díá fún Oǹderè
Ọmọ afàdán ṣẹ̀bọ
Nítorí ọmọ

Òun lè bímọ báyìí?
Ni Ońderè dáfá sí
Wọ́n ní ẹbọ ni ó wáà rú
Ó sì rú u
Ìgbà tó rúbọ tán
Ó sì bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ...(3)

Nínú ẹsẹ Ifá òkè yìí, a rí i bí Ọ̀rúnmìlà ti sọ̀rọ̀ Ońderè dayọ̀ nípa fífún un ní ọmọ tí ó ti jẹ́ ìṣòrò rẹ̀. Àjàyí (2002:1) sọ pé káàkiri àgbáyé ni àwọn ènìyàn ti máa ń ṣe àyẹ̀wò nǹkan lọ́nà kan tàbí òmíràn nígbàkugbà tí wọ́n bá rò pé ó yẹ láti ṣe bẹ́ẹ̀. Kí wọ́n tó lè ṣe ìpinnu tó fẹsẹ̀ rinlẹ̀ lórí ìṣòro-kí-ṣorò tó bá dojúkọ wọ́n, pàápàá jùlọ nígbà tí ọkàn wọn bá ń ṣiyèméjì lórí ohun tó lè jẹ́ àyọrísí ìwà tí wọ́n bá hù tàbí ohun tí wọ́n bá ṣe. Ìgbàgbọ́ tó rọ̀ mọ́ ṣíṣe bẹ́ẹ̀ ni pé àyànmọ́ wà, ó lè jẹ́ èyí tó dára tàbí èyí tí kò dára, èyí tí ìgbàgbọ́ wà pé àwọn adífá/babaláwo lágbára láti tún ṣe.

Adífá/babaláwo ni yóò dábàá ọ̀nà àbáyọ èyí tí ẹni tó wá ṣe ìwádìí yóò yẹ̀wò kí ó tó mọ ohun tí yóò ṣe lórí ìṣòro bẹ́ẹ̀. Ẹni tó wá ṣe àyẹ̀wò yóò ní ìgbàgbọ́ gidi nínú adífá, èyí ni yóò sì sọ bí àṣeyọrí rẹ̀ yóò ṣe tó (Àjàyí, 2002:6). Babaláwo tí à ń sọ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí ó gbọ́fá yékéyéké, tí kò gbọdọ̀ bepo-bọyọ̀ gégé bí Àjàyí (2002) ṣe sọ. Ó ní tí babaláwo kò bá kọ́ Ifá, kí ó mọ̀ ọ̀n dunjúdunjú, kò ní í lè sọ ìtumọ̀ Odù tí ó hù lójú ọpọ̀n-Ifá, ìsọkúsọ ni irúfẹ́ babaláwo bẹ́ẹ̀ yóò máa sọ fún ẹni tó wá dífá. Fún ìdí èyí, oníbárà rẹ̀ tí kò ní ìgbàgbọ́ nínú Ifá yóò sọ pé Ifá kò lè rí ohun gbogbo tán, bẹ́ẹ̀ sì ni:

Ọ̀pẹ̀ ò ṣèrú
Oníkin ni ò gbọ́fá
Ohun a bá bifá,
Nifá á sọ (Abímbọ́lá, 1976 nínú Àjàyí, 2002:6).

Ohun tí Àjàyí (2002) ń sọ ni pé èkọ́ṣẹ́ ṣe pàtàkì nínú Ifá, babaláwọ́ tí ó bá kọ́ Ifá yékéyéké yóò lè rí ìṣòro oníbárà rẹ̀ nínú Odù tó hù lójú ọpọ̀n-Ifá.

Nígbà tí ẹni tí ó fẹ́ ṣe àyẹ̀wò bá dé ọ̀dọ̀ babaláwo, àwọn ìgbésẹ̀ kan máa ń wayé. Àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí ni àwọn onímọ̀ lóríṣiríṣi tí ṣíṣẹ́ lórí rẹ̀ bí ìhun tí ẹsẹ Ifá máa ń ní. Èyí ní yóò gbé wá dé ìpele tí ó kàn nínú iṣẹ́ yìí tí a pè ní akitiyan àwọn onímọ̀ ìṣàájú lórí ìhun ẹsẹ Ifá. Lẹ́yìn náà ni a ó wo akitiyan tí Ọjọ̀gbọ́n Bádé Àjàyí náà ṣe láìpẹ̀ yìí láti ṣe àtúnpín ìhun ẹsẹ Ifá.

Akitiyan Àwọn Aṣáájú lórí ìhun Ẹsẹ Ifá

Gégé bí èro Ọlábímtán (1980:11), ó ní oríṣi ewì àbáláyé kọọkan ló ti ní ọnà tí wọn n gbà to èrò nínú wọn, díè kíún sì ni ìyípadà tí akéwì kan lè ṣe lórí èrò bẹẹ. Èyí kò sì yọ ẹsẹ Ifá, gégé bí òkan lára ewì àbáláyé, sílè. Àwọn ohun tó jẹ tíórí ìfojú-ààtò-wò lógún gégé bí Adéyẹmí (2006:13) ṣe sọ ni ìró ohùn, ààtò tàbí èrò inú iṣẹ́ ọnà, nígbà tí tíórì ìfojú-ìhun-wò rí iṣẹ́ ọnà bí ohun tí ó wà lódindi, ṣùgbón tó jé pé nípele nípele bí àlùbọsà oníṣu ni wọn tèlé ara wọn. A gbódò wo èka kọọkan tàbí awé kọọkan kí á rí bí wọn ṣe so móra tó fi di odindi (Adéyẹmí, 2006:17). Lára àwọn onímọ̀ tí wọ́n tí ṣíṣẹ́ lórí ìhun ẹsẹ Ifá ni Raymond (1964), Bascom (1969), Abímbọ́lá (1976) àti Ọlátúnjí (1984). Ojú tíorí ìfojú-ààtò-wo àti ìfojú-ìhun-wo ni àwọn onímò wònyí fi pín ìhun ẹsẹ Ifá.

Raymond (1964:2-6 nínú Ọlátúnjí 1984:127)) ṣe àlàkalẹ̀ ìpín mẹ́rin tí ẹ̀ṣẹ́ Ifá kan lè ní. Àwọn ìpín mẹ́rin náà ni ìfáárá, sisọ ìṣoro oníbèérè, ẹ̀bọ rírú, àti ìgbọ̀ràn/àìgbọ̀ràn oníbèérè. Bascom (1969) sọ pé ìhun mẹ́ta ni ẹ̀ṣẹ́ Ifá ní. Àkọ́kọ́, babaláwo yóò kọ́kọ́ ṣe ìfáárá, èyí ni pé yóò kó ọ̀pẹ̀lẹ̀ síta láti kàn sí Ifá. Èkejì r.: Ifá kíkì funra rẹ̀, tí babaláwo yóò ki Ifá lọ jántìrẹ̀rẹ̀. Ẹ̀kẹ́ta ni síso Ifá tí ó kì mọ́ oníbèérè. Èyí ni yóò kì mọ́ ìbéèrè ẹni tí ó wá dífá, tí yóò sì sọ ẹ̀bọ tí yóò rú fún un. Abímbọ́lá (1976:43-62) ní tirẹ̀ ṣàlàyé pé ẹnu ẹ̀ṣẹ́ Ifá tí babaláwò kì nìkan ni ó gbọ́dọ̀ jẹ́ ìhun ẹ̀ṣẹ́ Ifá. Ó wá pín ẹ̀ṣẹ́ Ifá sí ọ̀nà mẹ́jọ báyìí:

-ìgbésẹ̀ kìíní ni a máa ń rí orúkọ tàbí ìnagijẹ babaláwo tó ti dífá ṣaájú. Púpọ̀ nínú wọn ló sáábà máa ń jẹ́ orúkọ ìnagijẹ tàbí oríkì babaláwo tí ọ̀rọ̀ kàn. Ìpín yìí ṣe pàtàkì fún àwọn babaláwo nítorí láìjúbà àwọn babaláwo tó ti kọjá, pàtàkì ẹ̀ṣẹ́ Ifá kò ní í farahàn. Abímbọ́lá ní ìpín yìí ló mú kí ẹ̀ṣẹ́ Ifá kan jẹ́ àkọsílẹ̀ tòótọ́ nípa ohun tó ti ṣẹlẹ̀ ṣáájú. Ó ní, ó ṣeéṣe kí orúkọ bẹ́ẹ̀ máà jẹ́ ti ènìyàn gidi, kí ó jẹ́ orúkọ ẹranko, ẹ̀yẹ tàbí ohun ọ̀gbìn. Wọ́n á sọ àwọn nǹkan wọ̀nyí di ènìyàn nípa gbígbé àbùdá ènìyàn wò wọ́n, kí ìbáṣepọ̀ pẹ́kípẹ́kí lè wà láàrin ìtàn tí wọ́n fẹ́ sọ.

-ìgbésẹ̀ kejì ni dídárúkọ ẹni tó wá dífá (ẹni tí a dífá fún) nípa lílo gbólóhùn bí i "a díá fún...". Ẹni tí a dífá fún lè jẹ́ ènìyàn kan tàbí odidi ìlú kan. Bí àpẹẹrẹ, "A díá fún Ṣóoróyè, ọmọ aṣaworoko".

-ìgbésẹ̀ kẹ́ta ni ìdí tí a fi dífá fún ẹni tí a dífá fún. Ìdí tí a fi dífá lè jẹ́ àìsàn, ikú, ọ̀tá, àìláya, àìbímọ tàbí àìlówó, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ, "ẹkún ọmọ ní í sun".

-ìgbésẹ̀ kẹ́rin ni síso ohun tí Ifá ní kí oníbèérè ṣe. Bí àpẹẹrẹ:

Wọ́n ní ó káakí Mọ́lẹ̀,
ó jàre,
ẹ̀bọ ní ó ṣe".

-ìgbésẹ̀ karùn ún ni ẹ̀ṣẹ́ Ifá yóò sọ ìgbọ̀ràn tàbí àìgbọ̀ràn oníbéèrè sí ohun tí wọ́n ní kí ó ṣe ní ìgbésẹ̀ kẹ́rin. Bí ó bá gbọ́ràn, a óò gbọ́ gbólóhùn bí í "Ó sì rú u". Ní ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, bí ó bá ṣe àìgbọ̀ràn, a máa gbọ́ gbólóhùn bí i:

Ó pawo lékèé
Ó pèṣù lólè,
Ó wọ̀run yàn yàn yàn
Bí ẹni tí ò ní kú mọ́ láyé
Ó wá kọtí ọ̀gbọin sẹ́bọ.

-ìgbésẹ̀ kẹ́fà máa ń sọ àtubọ̀tán ìgbọ̀ràn tàbí àìgbọ̀ràn oníbèérè sí Ifá. Lẹ́yìn tí ó ti rúbọ tán tàbí kọ̀ rú u, kí ló wá ṣẹlẹ̀ sí irú ẹni bẹ́ẹ̀. A máa ń rí gbólóhùn bí i "ìgbà tó rúbọ tán, ló bá bẹ̀rẹ̀ sí í lájé".

-ìgbésẹ̀ kéje máa ń sọ nípa ìhùwàsí oníbéèrè sí ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣẹlẹ̀ sí i lẹ́hìn ìgbọ̀ràn tàbí àìgbọ̀ràn rẹ̀ sí Ifá. Lábẹ́ èyí, tí oníbéèrè bá gbọ́ràn, a máa ń sáábà rí gbólóhùn bí i:

Ó ń yin àwọn awo rẹ̀,
àwọn awo rẹ̀ ń yin'fá
Ó ya ẹnu kótó,
Orin awo ló bọ́ sí i lẹ́nu
Ẹṣẹ tí ó nà,
Ijó fà á.

Bí ó bá ṣe àìgbọràn, a máa ń gbọ́ gbólóhùn bí i "Àyìn-ódì ní ń yin àwọn awo rẹ̀". Ìpín yìí ṣe pàtàkì nitorí pé ó ṣe àfihàn ìdájọ́ ẹni tó wá dífá nípa ohun tó ṣe, ó sì ṣọ pàtàkì ìgbọràn.

-ìgbésẹ̀ kéjọ dúró gẹ́gẹ́ bí ìgúnlẹ̀ fún gbogbo ìtàn tó wà nínú ẹṣẹ Ifá náà. Èyí dúró gẹ́gẹ́ bí ẹ̀kọ́ tí a rí kọ́ nínú ẹṣẹ Ifá náà. Ó dúró bí ìkìlọ̀ fún ẹni tí kò fẹ́ rúbọ Ifá. Bí àpẹẹrẹ:

rírú ẹbọ ní í gbe ni
àìrú kì í gbèèyàn.
Ẹ wá bá ni ní wọ̀wọ́ ọmọ...

Adétúnjí (1984:127-133) ṣàlàyé pé ìgbésẹ̀ méje péré ló yẹ kí ẹṣẹ Ifá ní. Ó gbà pẹ̀lú ìgbésẹ̀ kìíní Abímbọ́lá (1976), ṣùgbọ́n ìgbésẹ̀ kejì àti kẹ́ta ní ó papọ̀ di ọ̀kan ṣoṣo. Èyí ló mú kí ìpín ẹṣẹ Ifá Ọlátúnjí (1984) jẹ́ méje.

Ṣáájú, àwọn onímò ti ṣọ àlèébù tí tíorí ìfojú-ààtò-wò àti tíórì ìfojú-ìhun-wò ní. Lára àléébù béè ni pé, nínú tíórì ìfojú-ààtò-wò, lítírẹ̀ṣò kò ní àjọṣepò pèlú àwùjọ, béè sì ni tíórì ìfojú-ìhun-wò ti fúnka mó ìhun gbólóhùn tí ó wà nínú iṣẹ́ lítírẹ̀ṣò jù. Àìpẹ́ yìí ni Àjàyí (2002) ṣe akitiyan láti ṣàtúnpín ìhun ẹṣẹ Ifá sí ọ̀nà mẹ́ta gbòòrò tí à óò gbé yẹ̀wò ní ìpele tí ó kàn báyìí.

Ìṣàtúnpín Ìhun Ẹṣẹ Ifá tí Bádé Àjàyí là kalẹ̀

Nínú iṣẹ́ tí Ọjọ̀gbọ́n Bádé Àjàyí ṣe tí ó pè ní *Ifá Divination: Its practice among the Yorùbá of Nigeria* (2002) ni ó ti ṣe àtúnpín ìhun ẹṣẹ Ifá. Àkíyèsí tí a ṣe nínú ìṣàtúnpín yìí ni pé, bí ó tile jé pé ẹṣẹ Ifá máa n ní ààtò tirè lótò gégé bí àwọn ewì àbáláyé mìíràn, Àjàyí (2002) ṣe àgbékalè ìhun ẹṣẹ Ifá nípa lílo tíórí ìfojú-ìhun-a-so-pò-mó-ìṣẹ̀lè-àwùjọ-wò. Tíórì yíi, gẹ́gẹ́ bí Adéyẹmí (2006:20) ṣe ṣọ, gbàgbó pé "tí a bá fẹ ṣe ìtúpalè tí ó lóòrìn a gbódò ṣe ìwádìí ìbẹrẹ irú lítírẹ̀ṣò bẹ́ẹ̀, kí ni èrèdí iṣẹ́ lítírẹ̀ṣọ, níbo ni orisun rè, kí ló fa orisun rè..." Tíọrì yìí tún ṣọ síwájú sí i pé bí a bá wo èhun inú iṣẹ́ lítírẹ̀ṣò kan dáadáa, ó yẹ kí ó fara jọ èhun ìbágbépò àwújọ (Adéyẹmí, 2006:20). Èyí ni a ṣe àkíyèsí rè nínú iṣẹ́ Àjàyí (2002) nípa pé ó so ìpín ẹṣẹ Ifá tirè mó àwùjọ. Àjàyí ṣàlàyé pé ìhun mẹ́ta ni ẹṣẹ Ifá kan máa ń ní, yálà Ifá kékeré tàbí ńlá. Ìpín mẹ́ta náà ni ó pè ní; ọ̀rọ̀ àkọ́ṣọ, ìtàn Ifá, àti ọ̀rọ̀ àṣọkágbá (Àjàyí, 2002:27). Ní báyìí, a óò ṣàlàyé kíkún lórí àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà.

(1) **Ọ̀rọ̀ àkọ́ṣọ**: Èyí ni ó jẹ́ ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́. Lára àwọn ọmọ abẹ́ ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ yìí ni:

- Ìkíni. Oníbèérè yóò kí babaláwo. Bí àpẹẹrẹ, "Àgò onílé o/baba awo o". Ìdáhùn: "Àgò ó yà o".
- Kí ni ohun tó gbé oníbèérè dé ọ̀dọ̀ babaláwo. Àpẹẹrẹ, "Ẹ jọ̀wọ́ mo fẹ́ ṣe ìbéèrè ni/Mo fẹ́ bá Ifá sọ̀rọ̀".

- Babaláwo gbé ọ̀pẹ̀lẹ̀ jade. Oníbéèrè yóò dàníyàn. Léyìn èyí, babaláwo yóó juba Ifá - "iwájú ọpọ́n o gbọ́, èyìn ọpọ́n o gbọ́, olùmọ̀ràn lọ́tùn ún, ọlọ̀mọ̀ràn lósi. Ìwọ lawo, èmi lọ̀gbẹ̀rì, má fire pebi, ma fire pebi, má fòlòlò fọhùn" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Babaláwo yóò gbé ọ̀pẹ̀lẹ̀ ṣánlẹ̀ kí Odù kan hù.

(2) **Ìtàn Ifá:** Èyí ni ìgbésẹ̀ àárín níbi tí a ti rí àwọn nǹkan wọ̀nyí:
- Babaláwo yóò sọ Odù tó hù, yóò wá ki Odù náà.
- Yóò sọ ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ Odù náà. Ìtàn yìí ni kíki ẹsẹ Ifá.
- Yóò jíṣẹ́ tí Ifá rán sí oníbèérè nípa lílo ọ̀rọ̀ geere. Bí wọ́n bá fẹ́ wádìí síwájú sí i, babaláwo yóò tún Ifá dà.

(3) **Ọ̀rọ̀ àsọkágbá:** Èyí ni ìgbésẹ̀ ìparí.
- Oníbèérè yóò sọ èrò ọ̀kan rẹ̀ lórí Odù tó hù tí babaláwo ṣàlàyé fún un.
- Babaláwo yóò wá fín ìdi kókò. Bí àpẹẹrẹ, tí ó bá ṣe pé ikú tàbí àrùn ló yọ́ lójú ọpọ́n, babaláwo wádìí ẹni tí ikú mú tàbí ara ẹni tí àrùn wà. Ìbò ni a fi ń wá èyí, nípa gbígbé ọwọ́ Ifá ní àkọ̀tun. Èyí ló fa irú ìpèdè yìí:

Ọ̀pẹ̀ ò ṣèrú
Oníkì ni ò kì í
Ohun a bá bifá ni Ifá ń sọ.

- Ẹbọ yíyàn. Babaláwo lè ka àwọn èròjà ẹbọ sílẹ̀. Ọ̀rọ̀ geere ni yóò fi sọ ọ.
- Ẹbọ rírú. Bí oníbèérè bá ti múra lọ́wọ́, yóò ṣe é tàbí kí ó padà wáa rúbọ náà. Babaláwo yóò tún máa ki Ifá síwájú sí i "rírú ẹbọ ní í gbe'ni, àìrù ẹbọ kì í gbènìyàn" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìgbésẹ̀ náà bí Àjàyí ṣe gbé e kalẹ̀:

I. **Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ (Ìbẹ̀rẹ̀)**

Oníbèérè: Àgò onílé o.
Babaláwo: Àgò ó yà o.
Oníbèérè: Ẹ jọ̀wọ́ mo fẹ́ ṣe ìbéèrè ni./
Mo fẹ́ẹ́ bá Ifá sọ̀rọ̀.
Babaláwo: (**Awo gbé ọ̀pẹ̀lẹ̀ jade**) Ẹ dàníyàn.
Ẹ mú àníyàn wá (Oníbèérè dàníyàn jẹ́ẹ́jẹ́).
Babaláwo: (Awo di ọ̀pẹ̀lẹ̀ mú láàárín, ó nà án síwájú rẹ̀.)
Ọ̀pẹ̀lẹ̀ ó gbọ́ o, Akinòòsà.
Balógun lóde ọ̀run, Olùmọ̀ràn lóde Ọ̀wọ̀
Aríhìnín rọ́hùnún, ó gbọ́ ohun tó wí o
Ìwọ lawo, èmi lọ̀gbẹ̀rì
Ohun tó wí ìwọ ló gbọ́
Bí ó bá ti rí ni o wí o
Ma fire pebi, má fibi pere
Iwájú ọpọ́n o gbọ́, èyìn ọpọ́n o gbọ́.
Olùmú lọ́tùn-ún, Olùkànràn lósì
Àárín ọpọ́n o gbọ́ ìta ọ̀run
Ilẹ̀ o gbọ́ Agbálágùdé

Àtiwáyé ọjọ́, àtiwọ̀ oòrùn
Ajé ìwọ nàà gbọ́
O gbọ́ tí olówó yìí wí o
Ire (Babaláwo da ọ̀pẹ̀lẹ̀)
Èjì-Ogbè, baba Ifá (Odù tó hù).
Ire ni Ifá lóun rí.
Ire owó, aya, ọmọ. (Awo gbé ọ̀pẹ̀lẹ̀ ṣánlẹ̀)
Bẹ́ẹ̀kọ ni awo yìí? (Ó gbé ọ̀pẹ̀lẹ̀ ṣánlẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì).
Ọwọ́ ọ̀tún (Owó ẹyọ tó dúró fún "bẹ́ẹ̀ni" ni adìbò/
Oníbéèrè kọ́kọ́ jù sílẹ̀).

II. Ìtàn Ifá (Àárín)

Babaláwo: (Awo bẹ̀rẹ̀ síí túmọ̀ ohun tí Ifá wí, ó ń ki Ifá). Ẹni tó dá Èjì-Ogbè, Ifá ní kí oníyẹn rúbọ. Ifá lóun ò níí jẹ́ ó tẹ́. Ifá lóun ò níí jójú ó tì í. Ifá pé gbogbo ohun tí eléèni bá ti dáwọ́lé ni ó máa yọrí sí dáadáa. Ifá pé kí oníyẹn ó rúbọ ajé, kó rúbọ obìnrin, kó rúbọ ọmọ, pé ire tó torí rẹ̀ dáfá sí, pé ire nàà ó sùn ún bọ̀.
Èdúdú ò wulẹ̀ dú,
Òkùnkùn ò wulẹ̀ kùn.
Jálagbà lawo àgbàrá
A dífá fún Atẹ́nilárà awo òkun
Èdúdú ò wulẹ̀ dú
Òkùnkùn ò wulẹ̀ kùn
Jálagbà lawo àgbàrá
A dífá fún Atẹ́nilárà awo ọ̀sà
Èdúdú ò wulẹ̀ dù,
Òkùnkùn ò wulẹ̀ kùn
Jálagbà lawo àgbàrá
A dífá fún Atẹ́nilárà awo àtan omi
Atẹ́nilárà awo òkun.
Ẹni tí kò bá ní lọ́wọ́ kò ní ìsinmi
Bẹ́ẹ̀ ni ti awo ọ̀sà
Bẹ́ẹ̀ ni ti àtan omi.

Ọ̀rúnmìlà ló wá dáfá pé àwọn atẹ́nilárà yìí, mẹ́tẹ̀ẹ̀ta lè pé fóun, òun ò lè tẹ́ báyìí?. Wọ́n ní ẹbọ ni kó rú. Ọ̀rúnmìlà sì rúbọ.

Atẹ́nilárà awo òkun lorúkọ à á pe ajé
Ifá pé kí eléèni ó rúbọ ajé
Atẹ́nilárà awo ọ̀sà lorúkọ à á pe obìnrin
Ifá pé kí oníyẹn ó rúbọ obìnrin.
Atẹ́nilárà awo àtan omi lorúkọ à á pe ọmọ
Ifá pé kí olúwa rẹ̀ rúbọ ọmọ.

Ọ̀rúnmìlà lówó lọ́wọ́, ó lóbìnrin, ó sì bímọ, ni inú rẹ̀ wá dùn ní ń pé:

Orí mi àpéré
Àyà mi àfobì kàn.
Òrìṣà-àgbò kó má mà jẹ́ kí Atẹ́nilárà ó tẹ́ ni.

Ifá póun ò ní í jẹ́ kí eléèni ó tẹ́. Ifá pé òun óò jẹ́ ire ó tó oníyẹn lọ́wọ́. Àgbébọ̀ adìẹ, òkẹ́ méfà, eku àti ẹja ni ẹbọ rẹ̀.

III. Òrọ̀ Àsọkágbá (Ìparí)

Oníbèérè: Ẹ ṣeun awo. Gbogbo ohun tí mo dàníyàn ni ẹ já nígbà tí ẹ̀ n kifá. Mo gbà láti rú ẹbọ tí ẹ kà sílẹ̀ fún mi, ṣùgbọ́n ó di ọ̀la kí ẹ tó rí mi. (Oníbèérè rúbọ ní ọjọ́ kejì) (Àjàyí 2002:29-35).

Àjàyí (2002:27) fi kún un pé ìdí tí ó fi pín ihun Ifá sí ọ̀nà méta ni pé, ní ti àwọn ìpín àtẹ̀hìnwá, ó ṣeéṣe kí ìgbésẹ̀ méje (Ọlátúnjí, 1984) tàbí ìgbésẹ̀ méjọ (Abímbọ́lá, 1976) má à pé nínú ẹsẹ Ifá kan, ṣùgbọ́n ní ti ọ̀nà méta tó là kalẹ̀ yìí, gbogbo ìgbésẹ̀ yìí ni yóò pé nínú ẹsẹ Ifá. Àjàyí sọ síwájú sí i pé ó ṣeéṣe kó má ní gbogbo ọmọ abẹ́ rẹ̀, ṣùgbọ́n dandan ni kí ó ní ìbẹ̀rẹ̀, àárin àti ìparí. Ìyàtò kan gbòógì tí a rí nínú iṣẹ Àjàyí, gégé bí a ṣe rí i nínú àpilèkọ yìí ni pé, ó fi bí àwùjọ Yorùbá ṣe rí hàn, pàápàá jùlọ nígbà tí oníbèérè bá ti n dásẹ̀ wọ ilé babaláwo tití di ìgbà tí yóò kúrò níbè. Ó fi gbogbo ìṣèlè tí ó máa n wáyé nílé babaláwo hàn bí ìran, bẹ̀rẹ̀ láti ibi ìkíni tití di ìgbà tí oníbèérè yóò dágbére láti padà sí ilé rè. Èyí kò rí béè nínú ìpín ihun ẹsẹ Ifá àwọn onímò ìṣàájú. A lè pe èyí gégé bí àmúyẹ fún iṣẹ Àjàyí (2002), nítorí pé ó ní àsopò pèlú ògangan ipò ìṣèlè ní àwùjọ Yorùbá. Ní ti ìjọra iṣẹ Àjàyí pèlú ti àwọn aṣáájú, a rí i pé bákan náà ni ọmọ ṣe orí nípa ẹsẹ Ifá, kíkì rè kò yàtò, béè sì ni àkóónu tí à n rí nínú ẹsẹ Ifá kò yàtò láti ibi kan sí ibòmíràn.

Ìgúnlẹ̀

Nínú iṣẹ́ yìí ni a ti ṣàgbéyẹ̀wò akitiyan Ọjọ̀gbọ́n Bádé Àjàyí nínú ìṣàtúnpín ihun ẹsẹ Ifá. Kí a tó lè ṣe èyí, a wo ìpín ìṣàájú tí àwọn onímọ̀ bí i Raymond (1964), Bascom (1969), Abímbọ́lá (1976) àti Ọlátúnjí (1984) ti ṣe lórí ihun ẹsẹ Ifá. Èyí ló tó wa sọ́nà láti mọ ibi tí iṣẹ́ dé dúró lórí ìpín ihun ẹsẹ Ifá. Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn sí wa nínú pépà yìí, iṣẹ́ Àjàyí (2002) ni ó ṣ jẹ́ àkọtun lórí ihun ẹsẹ Ifá. Àjàyí pín ihun ẹsẹ Ifá sí ọ̀nà méta gbòòrò tí í ṣe; òrọ̀ àkósọ, ìtàn Ifá, àti òrọ̀ **àsokágbá**. **Ní** èrò tiwa, ihun ẹsẹ Ifá tí Àjàyí (2002) la kalẹ̀ rọrùn, ó sì kún ju ti àtẹ̀hìnwà lọ, **nítori gẹ́gẹ́** bí àgbékalẹ̀ Àjàyí (2002), àgbékalẹ̀ ihun ẹsẹ Ifá ti bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà tí oníbéèrè ti dásẹ̀ wọ ilé babaláwo tití di ìgbà tí ó bá jade. Bí ó sì tile wù kí ó rí, yálá Ifá kékeré tàbí ńlá, yóò ní ìbẹ̀rẹ̀, àárin àti ìpari.

Àwọn Ìwé tí a lò

Abímbólá, W. (1976). *Ifá: an exposition of Ifá literary corpus.* Ibadan: Oxford University Press.

Abímbólá, W. (1977). *Àwọn ojú odù mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún.* Ibadan: Oxford University press.

Adéyẹmi, L. (2006). Tíọrì lítírẹ́ṣọ ní èdè Yorùbá. Ijebu-Ode: Shebiotimo publications.

Àjàyí, B. (2002). *Ifá divination: its practice among the Yorùbá of Nigeria.* Ijebu Ode: Shebiotimo publications.

Akintola, A. (1999). Yoruba ethics and metaphysics. Ogbomoso: Valour publishing ltd.

Asáolú, Y. (1981). *Ìwé ilẹ́wọ Ifá Yorùbá fún àwọn akẹkọọ.* Ilesa: Fatiregun press & publishing co.

Asawale, P. (2011). The relevance of images in Yorùbá traditional worship to effective Christian evangelisation. In W.O. Aso (Ed.), *The relevance of images in worship: a path to evangelization* (pp. 1-8). Ekpoma: Seminary of All Saints.

Bascom, W. (1969). *Ifá divination: communication between gods and men in West Africa.* London: Indiana University press.

Ẹlébúibọn, Y. (2004). *Ifá: the custodian of destiny.* Ibadan: Penthouse publications.

Ọlabimtan, A. (1980). Ọgbọn itọpinpin ewì Yorùbá. Lagos: Macmillan Nig. publishers Ltd.

Ọlátúnjí, O.O. (1984). *Features of Yorùbá oral poetry.* Ibadan: University press limited.